# ÌLÀNÀ ÀÌṢE OJÚṢÀÁJÙ

Mercy Health Services (MHS) máa ntẹ̀lé àwọn òfin ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ti Ìjọba Àpapọ̀ kìí sìí ṣe ojúṣàájú látàrí ìran, àwọ̀, orílẹ̀ ìbínibí, ọjọ́ orí, jíjẹ́ aláàbọ̀ ara, ẹ̀sìn, àṣà, èdè (títí kan ìdáṣáṣá tí ó mọ níwọ̀nba ní èdè Gẹ̀ẹ́sì àti èdè abínibí), jíjẹ́ aláàbọ̀ ara àfojúrí tàbí ti ọpọlọ, ìdánimọ̀ tàbí ìṣàfihàn ẹ̀yà akọ-n-bábo, ẹ̀yà akọ-n-bábo (títí kan àwọn àbùdá ẹ̀yà akọ-n-bábo, àwọn àpèjúwe láarín ẹ̀yè akọ-n-bábo, oyún níní tàbí àwọn ààyè tí ó níí ṣe pẹ̀lú rẹ̀, ìdánimọ̀ ẹ̀yà akọ-n-bábo àti àwọn ìrònú tí ó rọ̀ mọ́ ẹ̀yà akọ-n-bábo), ipò ọrọ̀-ajé àti ti àwùjọ, ìgbàgbọ́ òṣèlú, àwọn ìwà ọmọlúàbí ti àṣà àti ara ẹni, ipò ìgbéyàwó, àìsàn, agbára láti sanwó, ìlànà ìtọ́jú ti tẹ́lẹ̀ tàbí àpapọ̀ yòówù nínú rẹ̀ tí a bá nsọ gbígbani sí ilé-ìwòsàn, níní ànfàànì sí ìtọ́jú tàbí iṣẹ́.

Bákan náà MHS máa npèsè àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú bíi:

- Àwọn ohun èlò ìrànlọ́wọ́ tàbí iṣẹ́ ìtọ́jú ọ̀fẹ́, àti àwọn ìyípadà tí ó mú ọgbọ́n dání ní ọ̀nà tí ó bọ́ sí àkókò fún àwọn tí ó ní àbọ̀ ara láti báni sọ̀rọ̀ ní ọ̀nà tí ó múná dóko, bíi:
  - Àwọn ògbifọ̀ tí ó kún ojú ìwọ̀n fún àwọn ẹyọ ẹnìkọ̀ọ̀kan tí wọ́n ní àbọ̀ ara
  - Alàyé tí a kọ sílẹ̀ ní àwọn àwòṣe míràn (ohun tí a tẹ̀ ní ọ̀nà tí ó tóbi, ohùn, àwọn àwòṣe orí ẹ̀rọ míràn tí a lè ní ànfàànì sí, àwọn àwòṣe míràn)
- Àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ti ìrànlọ́wọ́ èdè lọ́fẹ̀ẹ́ tí ó bọ́ sí àkókò fún àwọn tí èdè abínibí wọn kìí ṣe èdè Gẹ̀ẹ́sì, bíi:
  - Àwọn ògbifọ̀ tí ó kún ojú ìwọ̀n
  - Títúmọ̀ àwọn ìwé orí ẹ̀rọ àti èyí tí a kọ

Tí o bá nílò àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú yìì, ìwọ tàbíaṣojú rẹ lè kàn sí **Alábòójútó Iṣẹ́ Nọ́ọ̀sì** tàbí ọmọ ikọ̀ ìtọ́jú rẹ míràn.

Tí o bá gbàgbọ́ pé MHS ti kùnà láti pèsè àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú yìí tàbí ó ṣe ojúṣàájú ní ọ̀nà míràn, o lè fi aáwọ̀ kan kalẹ̀ pẹ̀lú: **Section 1557 Coordinator, 301 St. Paul Place, Baltimore, MD 21202, Ẹ̀rọ Ìbánisọ̀rọ̀: 410-332-9242 Ímeèlì: patientadvocate@mdmercy.com**. O lè fi aáwọ̀ kan kalẹ̀ lójúkoojú, nípasẹ̀ ìfìwéránṣẹ́ tàbí ímeèlì. Tí o bá nílò ìrànlọ́wọ́ láti fi aáwọ̀ kan kalẹ̀ **Alágbàwí Agbàwòsàn**, kan wà ní àrọ́wọ́tó láti ràn ọ́ lọ́wọ́ nípa kíkàn sí àdírẹ́sì ímeèlì tàbí nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tí a tòkọ sí òkè yìí.

Bákan náà o lè fi ẹ̀sùn ẹ̀tọ ọmọnìyàn kan kalẹ̀ pẹ̀lú U.S. Department of Health and Human Services, Office for Civil Rights, lórí ẹ̀rọ nípasẹ̀ Ojú Pátákó ti Office for Civil Rights Complaint, tí ó wà ní àrọ́wọ́tó ní https://ocrportal.hhs.gov/ocr/portal/lobby.jsf, tàbí nípasẹ̀ ìfìwéránṣẹ́ tàbí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ ní:

U.S. Department of Health and Human Services
200 Independence Avenue, SW
Room 509F, HHH Building
Washington, D.C. 20201
1-800-368-1019, 800-537-7697 (TDD)

Àwọn fọ́ọ̀mù ìfisùn wà ní àrọ́wọ́tó ní http://www.hhs.gov/ocr/office/file/index.html.

Ṣe àbẹ̀wò sí **mdmercy.com** fún ẹ̀dà àlàyé tí a pèsè nínú àfiyèsí yìí.